# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 822 LAGOS SATURDAY JUNE 2. — JUNE 9, 1962. KOBỌ MEJI (2D)


# Awon Elewon F'ake

## Kori Nilu Kabba, Ogba Ewon Di Budo – Ogun.

KABBA—Gbogbo awọn ọdaran enia ti nwọn wa nile tubu (Ọgba ẹwọn) ti awọn Ijọba Ibilẹ ni Bunu-Ijumu dapọmọ Kabba ti f'ake kọri lori ọrọ onjẹ ti nwọn nfun wọn ti ko to, ti ko si tun dara.

Onirohin wa sọ wipe awọn ẹlẹwọn na bẹrẹ si kọ orin ti nwọn maa nkọ ni asiko ogun, nwọn si fi ṣibi, penu abọmafọ ati agunjẹ wọn ṣe kọkọrọ ati ilu, ariwo pọ to bẹ gẹẹ, ti ọpọlọpọ awọn ara ilu ti pejọ lati mọ kini ohun ti o ṣẹlẹ.

Nigbati awọn ẹlẹwọn na de ẹnu-ọna abajade, ni nwọn kesi Oluṣọ wọn ti o duro lẹhin ilẹkun, wipe ki o ṣi ilẹkun, ki awọn jade to lọ si ọdọ Alakoso agbegbe ilu (Divisional Officer) lati lọ f'ẹjọ sun. Nigbati Oluṣọ wọn (Warder) kọ lati ṣi ilẹkun na, awọn ẹlomiran ti ngun ogiri lati fo jade lọ baa, ki nwọn le f'ọwọba.

Ṣugbọn laipẹ na ni Alakoso de, Malam Abubakar Yola, ti o si tu wọn ninu wipe on yio ṣe atunṣe gbogbo ẹsun wọn na.


**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell
Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger ; London
Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH


## Okunrin Kan Ku Lojo Ti Nwon We "Wonka" Fun Ni Sosi

OKITIPUPA—Li ọjọ ọsẹ ti o kọja yi ni ariwo ta ni ilu yi wipe ọkunrin kan, Jonathan Bayọdele, ti nwọn ṣeṣẹ we "wonka" (ṣe 'tẹbọmi) fun ni Ṣọṣi awọn Serafu ku ni gbara ti o pada sile rẹ.

Onirohin wa fiye wa wipe bi ọkunrin na ti pada de'le, ọdọ aya rẹ, Ọmọwumi ti ko ba lọ si Ṣọṣi lọjọ na ni o lọ, o si ba wi wipe on nlọ ṣe nkan pataki ti o tobẹ ni Ṣọṣi, iyawo kole ba on lọ.

Iyawo na ni ọkan on kotilẹ pe "aila" lọjọ na rara nitoripe on ro wipe nkan buruku kan ni l'ati ṣẹlẹ ni adugbo awọn.

Lẹhin eyi, ni ọkunrin na wọ iyara rẹ lọ pe ki on f'ẹhin lelẹ diẹ ki akoko onjẹ to to, lati oju orun ni o ti yọ s'ọrun.


**LAGOS RACE CLUB**

**June Meeting 1962.**

Saturdays 9th, 16th, 23rd, 30th June, & 7th July, 1962.

Racing Starts at 2.45 p.m. each day of the Meeting.

DECLARATION.

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 1.45 p.m. on Racing Days.

ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)

ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in Advance at the Secretary's Office in the Paddock between the hours of 5 and 6 p.m. on the day preceding each day of the Meeting.

ADMISSION : 3/- per Day.
including Entertainment Tax.

CHILDREN.

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Eclosure.

# AWO IRAWO

Eyi ni awon nkan ti yio ṣe ṣẹ si ọ ni ọsẹ ti o mbọ.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) enikan ẹ̀yio wipe ki o yawon ni owo kan, ki o ro wo dara dara.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Bi o ba jẹ ẹnito o feran ki awon ma ca ẹ leto je ẹnilegbe, ki o jẹ ki awon sọ ẹ̀tọ fun ọ lọsẹ yi.

ARIES (Mar 21-April 20) Ṣe itọju nitori amọdi ẹ̀ẹ̀rẹ kan ti o fẹ kan si ẹ wo.

TAURUS (April 21-May 20) Lo ẹgbẹ ... yiri yẹrẹ awọ ṣe kan ti nwọn yio bẹ ọ lalẹ, ki o ma si fi wadu-wadu ra ọja.

GEMINI (May 21-June 21) B o ko ba yi ra wa padanu owo die ninu ... -ọja kan.

CANCER (Jun 22-July 23) Maṣe eki ... ti awon upẹ ... mbi ... o bo o loju, ti igbara-... ara ṣe iṣẹ sii.

LEO (June 24-Aug 22) Maṣe jẹki nkan kekere ba adehun ti o ba fẹ ṣe ... ko buru nitori ti o ba ṣe ... adehun na.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Maṣe jẹki wahala a mbọsahin-bọsọun ... ninu ọsẹ yi. Fi diẹ ninu awon nkan ti o fẹ ṣe si igbemiran.

LIBRA (Sep 23-Oct 24) Tẹjumọ iṣẹ rẹ, maṣe jẹki irohin buruku kekere kan ba ọ lọkan jẹ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Jẹki ... awọn nkan pataki ti o ba fẹ ṣe lọsẹ yi di ọsẹ miran.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) ... lodọ enikan ti yio fẹ gba ... kan lọwọ rẹ.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 21) ... ba iako ẹ diẹ larin ọsẹ yi, ... banujẹ, wa ba orirere kan pade laipẹ yi.

## Eru Aiye Ma Mba Mi!

(Lati ọwọ J. OLA WINS)

Awọn Yoruba ni ima pa lowe wipe "ẹru aiye ma mba mi" ko jọ pe a fẹni, ko jọ pe a ko fẹran ẹni, ẹru aiye ma mba mi, ẹ jare! ọrọ na ṣe pataki ni ode oni, nigbati a ba ri bi gbogbo aiye ti nlọ, ko si ọrẹ otitọ mọ. Ko si ẹniti o ṣe finu han mọ ni aiye wa ode oni, gbogbo aiye na wa nlọ bi

orin ti awon k... nkọ ni ... odun merin sehin, orin ... lọ bayi: "konkolo-jabel... "kaluku lo nṣe tirẹ konkolo-jabele."

Ṣe bi onikaluku ba ... tirẹ ti ko si wipe ẹnika... nwa ipalara fun ọmọnike... rẹ, Dada ko ma dara to ṣugbọn bi a ba wo aiye ... bi o ti ṣọwọ ri, ṣe ni aiy... na yio su enia. Ọpọlọp... rere ti enia ṣe, ti aiye ... ibi san pada ni koto ro ni tabi ẹniti a sọ ọrọ pamọ ... lọwọ to lọ ro fun ọlọrọ tabi ti o ti tọ ọlọpa lọ, tab... ẹniti a ya lowo ti a k... ṣe'we si, ti o tun taku wipe on kẹ! a bi ọgbẹni yi m... ọti yo ni? Enia le ya ow... ti o lo vẹn ki o ma ṣi iwe-adehun?

Ẹlomiran di ... ọwọn nitori ọrẹ, awọn ti o ya were ko lo nka, awọn asinwin pọ lọ jara; lori ọrẹ na ma ni. Igun se ore titi o pa lori, melo ni ki a ka ninu iwa ibajẹ ti o gba aiye kan, aiye wa di arisa-ari kọgbọn. Ani Ọgbẹni kan wo gbogbo aiye yi, o wa su gan an, ni o ba fi awọn ọmọ, iyawo, ẹbi ati ọrẹ rẹ silẹ, ni on paapa ba nlọ gbe inu igbo, o ni, o kuku san ki on maa gbe'nu igbẹ larin awọn eran ko ju enia lọ: o ni ibanujẹ ni awọn enia nko ba on ni arin wọn, oni o ri nfọ lagbaja ọla ọrun ndun tamẹdo ati bẹẹbẹ lọ ni on ba fi awọn enia inu aiye silẹ fun iwa buburu wọn.

Bẹni ọgbẹni kan ni aiye yi su on, o ni ko si enia rere mọ ni aiye yi, ni o ba fi wa bi y'o ti ṣe ba enia rere miran pade ti nwọn yo jọ ma gbe ni rẹpọ. Ọgbẹni yi ṣe wahala titi ko ri, o sun ni oju kan, o gbọ orin ti awọn ẹiyẹ nkọ lati fi yin Edumare' ya ni ẹnu lati gbo orin rere ati aladun bayi ni ẹnu awọn ẹiyẹ lasan.

O pinnu, o wa si ile, o tun nba awọn ọmọ enia gbe pọ, o wa ro wipe ko si ṣiṣe, on na ni lati tun iwa on papa-alara ṣe, nipa hihu iwa mimọ boya aiye le, tipa bẹ yi pada.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

Awọn ọ̀wọ̀ sisẹ tuntun ni ijẹri si ilọsiwaju

# UAC

## nran awọn ọmọ Nigeria lọwọ lati di onisọwo asiko ati lati da duro fun rawọn

Irinwo-le-ni-ẹgbafa (...,400) ọmọ Nigeria ni U.A.C. ti fun ni anfani ati ra awin oja ti o le ni ẹgberin-lẹ-ni ẹgbaa oke poundi (£26,000,000) lododun ... awin oja, imoran, ati itaramo ti awọn egbe onisọwo nfun tokunrin tobinrin awọn nran awọn onisẹ na lọwọ lati fọkanbalẹ jere lori iṣẹ nwọn.

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# ELETI--OFE

ANJUWON KO ŞE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI ỌFẸ." LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 822. SATURDAY JUNE 2- JUNE 9 1962.


## Egbe Omo Odudu-wa Di Bansa !

Awọn Yoruba ni nwọn ma npa l'owe wipe "Agbalagba kii wa l'ọja ki ori ọmọ tuntun wọ". Şugbọn gẹgẹbi nkan ti nlọ si ni ode t'oni, odabi ẹnipe awa Yoruba fẹ gbagbera, ati gbagbe awọn nkan wọnni ti a npe ni Işẹşe.

A ti gbagbe alajọbi, a si tun gbagbe Oduduwa ti a sọ wipe o bi gbogbo awa ọmọ ilẹ "K'aro, ao jire ?" sinu aiye yi. Bẹni nitori kia le feran arawa de'nu ni a se da ẹgbẹ ọmọ Oduduwa silẹ, şugbọn kini anfani ẹgbẹ na nigbati iru ede-aiyede, tẹmbẹlẹkun, inuni-bini ti ko kan aimọ iwa hu nla bẹsilẹ larin awọn ọmọ "K'arọ, ao jire"? lẹnu ọsẹ meji tabi mẹta sẹhin.

Ojẹ iyalẹnu fun ọpọlọpọ enia paapa awa ti a npe arawa ni "Ọmọ Oduduwa", ti a tun da ẹgbẹ silẹ ti a ko ri agba kan ti o le şe şai ! k'ama ri' ti o le gbe ẹgbẹ ọmọ Oduduwa dide lati p'ẹtu si ọrọ na titi ti o fi d'ogun ti o si d'ọdẹ bayi.

Anfani kini ẹgbẹ ọmọ Oduduwa nşe ? kini ẹgbẹ na wa fun ? "Mutun mu Bansa" bi ede awọn ọmọ alahusa, ni ẹgbẹ da lori ọrọ Ijọba Iwọ-orun yi. Bi igba ba şe gbe, agbe, bi ko si şe gbe, afọ, nitorina, ẹ tu ẹgbẹ na ka, nitoripe ko şe anfani kankankan fun ọmọ Yoruba.

---


## E Polowo Oja Nyin

Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe


# Iwe Si Olotu

## Aseju Baba Asete

Gbolohun ọrọ ti a fi şe-akọle wosika wa ọsẹ yi kun fun itumọ, o si kun fun oye. Bi o ti ma ye awo, bẹna ni ki o ma ye ogberi. Ẹnikan ko ju Oluwa Ọlọrun lọ, On ni Ẹni ipilẹ On na si ni ẹni ipari, On ni O mọ ohun gbogbo, ti o si le şe ohun gbogbo. Ko ni ẹnikeji, ko si ni ẹniti ao fi we.

Ẹda yowu ti o bajọ ara rẹ lo ju ju, nfi ara rẹ we Ọlọrun ni. Ẹnikẹni ti o ba sọ wipe "a fi on a fi on" mba Oluwa Ọlọrun to lọgbọgba. Suru ni ogun aiye, ifẹ ni akoja ofin. Ati pe laiye ko to nkan, etutu agba l'oju. Ẹnikẹni ti o ba tẹriba fun agba, a pẹ laiye, ẹniti o ba gba imọran agba, ko ni şe abamọ

Aşeju baba Aşetẹ, on ni o difa fun Ọrunmila Agbọniregun nigbati o nj on fẹ kọ ile kan ti yio ga kan ọrun.

Emi ni,

EKO Ọmọ Awo

---

## Ekunrin, Ewo Lo Se ?

Ẹ jọwọ, Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe Eleti-Ọfẹ lati kin Ọgbẹni S. Amọo lẹhin ninu ibere rẹ ti o kọ sinu iwe-irohin nyin niwọn nkan bi oşu kan sẹhin, ti o wipe, "Ewo ni Ẹkunrin nşe" ?

Ki nto wa si idalẹ oke-Okun ni mo ti mọ Ọgbẹni John Ẹkunrin l'oke Ọdẹ leti Ilọrin, ati bi o ti jiya pupọ to lori ọrọ ilu Oke-Ọdẹ pẹlu awọn alatilẹhin miran.

Şugbọn lati ẹnu bi ọdun mẹta sẹhin, a ko mọ ibiti o kọ iha si. Bi apa ọtun ni bi apa osi ni, kosi ẹniti o mọ. Bere-bere kii şibere; o yẹ ki Ọgbẹni Ẹkunrin paapa la ọrọ na ye wa.

Ẹ şe pupọ, a dupẹ fun aye ti ẹ gba m' Olodumare a bu si işẹ ọwọ nyin.

Emi ni,

Kumasi. M. Ọlatunde
Ghana.

---

## Awo Irawo

Ẹ jọwọ, ẹ ba wa dupẹ lọw. Ọgbẹni Awo Irawọ Eleti-Ọfẹ ti o ma nsọ nkan ti irawọ olukaluku wi fun un lọsọsẹ. Mo gbadun asọtẹlẹ ti Ọgbẹni Awo Irawọ na.

Mo ti nşe akiyesi ọrọ asọtẹlẹ tirẹ, mo si ri wipe o mbọ si gẹẹ fun mi. Gbogbo nkan ti o ba wi ni o nşẹ.

Ẹ jọwọ, ẹ tun ba wa kesii ki o ma tẹ iwe irawọ rẹ na fun wa lọsọsẹ ninu iwe irohin nyin oloyin mọmọ.

Emi ni,

W. Adeşina
EKO.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

K'AR'ỌKA RẸ

O ti pẹ ti emi Ayiluka ti nma sọ ọrọ kan bi owe, bi owe wipe, "Akoko ni yio kọ onikaluku wa." Njẹ akoko na ko wa nkọ gbogbo wa nisisiyi? Akoko nkọ olowo, nkọ talaka, bi akoko na si ti nkọ ọmọ-ẹru bẹsini o nkọ ọmọ onile; bi o ti nṣe waasi fun ọmọkewu, bẹsini o nkọ wosika fun baba alufa.

Ọrọ arọjunawa (austerity measure) ti o wa ni ode nisisiyi, gbogbo wa ni o ba wi pelu awọn ero ti o ṣẹṣẹ ti ilu Mẹka de laipẹ yi.

Ọrẹ mi, o jẹ mọ wipe ko si ọrọ a ngun ẹsin, ko si wipe gbogbo ẹbi ati awọn ọre nda aṣọ ẹgbẹjọda nibẹ. Ko si wipe ankọrin:

K'a r'ọko rẹ o e,
Ka r'ẹba ẹ,
Oke Arafa t'ogun,
K'a r'ọka rẹ.

O jẹ mọ wipe gbogbo awọn Alaja ati Alaji ti o de ninu irin ajo yi, nwọn nwọle bọsẹ lojiji ni? A ni ko si wipe a ngun ẹsin, a ngun mọto-ayọkẹlẹ, ko si jẹun-jẹun kan mọ; ko si ọrọ a nfi iyọ-ọbẹ si abẹ agbada lati lọ jẹ iresi.

OKUN LE, AGANYIN KO WẸ

Ọba mẹwa, igba mẹwa ni owe ti a le pa si bi ọrọ ti nlọ si ni Ibadan ile Oluyọle nisisiyi. Mo gbọ wipe gbogbo awọn obinrin ẹlẹyinju-ẹge gbogbo ti a ti mba jade faaji ni Eko-tedo, Gbagi ati ni Agọ-Ilọrin ni nwọn ti nko ẹru nwọn ti nwọn npada si ilu Eko nitori iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ nile Ipade Igbimọ Ijọba Iwọ-Orun ni aipẹ yi.

Gbogbo awọn ọkọ-asiko paapa ti nwọn ni iyawo bi mẹta mẹrin si ode, ni nwọn ti nfun wọn ni iwe-ikọsilẹ. Ọkan ninu awọn obinrin ẹlẹyinju-ẹgẹ na tilẹ fi iwe-ikọsilẹ tirẹ han mi nigbati a pade ninu ile-faaji kan ti nwọn npe ni "Garden o' Eden" ni Ebute Mẹtta ni alẹ ana.

ADELE ALAKOSO IJỌBA

Emi na ko ba awọn ọkọ wọn wi, aiye ti di aiye MAJẸKODUNMI nisisiyi. Iyẹn ni wipe enikan ko gbọdọ ni ẹnikan l a r i mọ ? ADEKOYEJỌ de, wa tuntun de, owo tuntun wọ'le.

Dokita Moses Adekoyejọ Majẹkodunmi, adele Alakọso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, mo ki ọ pupọ pe o ku orire, Liṣabi ilu Ẹgba a gbe ọ, o ko ni ṣee ti. Ṣugbọn ki o ma ṣe gbagbe emi Ayiluka, boya mo le ri ọna ti mo le fi ri owo tabua ya ni ọ d ọ Ijọba Ibadan. Emi paapa fẹ l'owo. Ọla ko pin sibi kan. Ọmọ-Ọla ni Ayiluka, ey iti o wu Ọlọrun Ọba ni o si nṣe lọwọ.

IJA-KO-DA-ỌLA

Ninu ọsẹ yi iwe meji ni mo ri gba lati ọdọ awọn ti o nkawe mi. Ikini lati ọdọ Ọgbẹni kan ti o njẹ Bọmọde'oku ni Oshogbo. Iwe ti o kọ simi na ni eyi.

"Ọgbẹni Ayiluka, o pẹ diẹ nisisiy ti mo ti nka iwe yin ninu iwe Eleti-Ọfẹ pelu awọn ọrẹ mi, ṣugbọn lati bi ọjọ mẹta ti edeaiyede ti bẹ silẹ larin awọn oṣelu wa ni Ibadan, a kotilẹ gbọ ki ẹnyin Ayiluka fẹ'nu kan ọrọ wọn na rara. Kilose?

"Ẹnyin oniwe irohin, ọrọ nyin kii y e w a nigbamiran, nitotoripe ni ọpọlọpọ igba ni ẹ npe ole wa ja, t i ẹ o s i tun pe oloko p e k i o w a s ọ ọ.

"Eyiti ẹ nda silẹ ninu ninu ruke – rudo yi paapa lo pọ; Ọtọ lejọ ti nwọn a ro, ọtọ ni irohin ti eo fi s'ode fun wa ka".

Mo fẹ ki ẹnyin ọkawe mi bami dupẹ lọwọ Ọgbẹni Bọmọde'oku pupọ ; mo si fẹ ki o mọ wipe awọn Yoruba ni o r u k ọ pataki kan ti nwọn nsọ ọmọ, orukọ na ni IJAKODỌ'LA.

# Bobby osere Idaraya



Ẹniti a nwo n i n u aworan y i n i Bobby Brightwell ti o jẹ ọkan ninu awọn ẹgbẹ e l e r e idaraya ti yio ba wọn sare ije ti nwọn m u r a rẹ nisisiyi nilu Rome.

A si ni igbẹkẹlẹ wipe yio yege ninu e r e sisa na yio si gba ami Golu b ọ wale f u n o h u n iyin ere na.

# E fi oju s'ona f u n Irohin aladun

**Lati Owo Ayiluka Eleti-Ofe**

# Ogbeni Butler Gba Ipo Olori Ile Ise Enia Dudu



ỌGBẸNI R. A. Butler ti a nwo ninu aworan yi ni nwọn gbe ipo olori ile iṣẹ enia dudu funu, ti yio maa ṣe eto ajumọṣepọ ilu Rhodesia ati Nyasaland eyiti o ti wa lọwọ akowe Igbimọ Ajumọṣe ti awọn ilu ti o mba Gẹsi ṣepọ.

Ọgbẹni M. D. Pennant, ti o ti jẹ akọwe Igbimmọ Iwadi ti Monckton ni yio jẹ akọwe nile iṣẹ enia dudu labẹ ọgbẹni Butler.

**Eyin Agbalagba E ba wa Tun Ile Yi Se, Agba Di Owo Yin. E ma Jeki O Baje.**


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

VACANCY - HYDROGRAPHIC RECORDER GRADE V

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Hydrographic Recorder Grade V. in the Harbours Department of the Nigerian Ports Authority.

QUALIFICATIONS:

Candidates should be in possession of the West African School Certificate with credit in Mathematics or the General Certificate of Education at Ordinary Level with passes in at least four subjects including English and Mathematics.

DUTIES:

Successful candidates will be required to assist and write down on all types of hydrographic survery work and take second angle in the launch when sounding. They will also be required to do tracings of hydrographic surveys and carry out minor computations. There will be an initial one year training on these duties and confimation of the appointments of those selected will depend on individual performances during this training period.

SALARY:

Scale S. £ (d) 143-11-330/345 per annum (Min.-£187).

METHOD OF APPLICATION:

All applications should give full details of age, qualification and experience, and forwarded to reach the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, P. M. B. 12588, Lagos, not later than 22nd June, 1962. Applicant in Government Departments and Statutory Corporations should forward their applications through their Heads of Departments who are requested to attach Confidential Reports before submitting them.

N. P. A. Notice No. 712.    BAYO KEHINDE

26th May, 1962.    Secretary to the Authority.

## E MA SE FI OMI SOFO MO




**E Kilo Fun Awon Omo Nyin**

# Bad drivers get warning

## It May Be Time For New Road Penalties Safety Chiefs Told

(By Our London Correspondent)

A new framework of penalties to punish "persistently bad and irresponsible road behaviour" way suggested yesterday by Lord Chesham, Parliamentary Secretary to the Transport Ministry.

He told 1,000 delegates to a National Road Safety Congress at Southport, Lancashire: "Road casualties are a many-headed monster. Progress in one direction is offset by a retreat elsewhere".

Lord Chesham was commenting on the big increase in the number of people killed and injured on the roads during the first six months of this year, compared with the same period last year.

He said that there had been 6.3 per cent more deaths and a 4.6 per cent increase in serious injury accidents.

"Quit rightly," he said, "the public need for Government initiative to combat this situation is urgent.

"There are some things which only the Government has the power and resources to undertake.

"Perhaps one of the most controversial aspects of road safety to-day is how to treat the druken driver. There have been columns of criticism and comment as to his degree of blame and, indeed, on what to do with him".

### Blood Check

LORD Chesham said: "Should the law be re-defined to make it easier for the police to bring proceedings in cases where they are comp'etely satisfied that a driver is unfit to drive through drink or drugs, although he is not incapably drunk in the ordinary sense of the phrase?"

"Should courts have regard to a chemical analysis of the quantity of alcohol in in the blood of a driver?"

He added: "Has not the time also come when persistently bad road behaviour must be recognised and dealt with by an entirely new framework of penalties for road traffic offences?"

Road deaths in 1960 rose by seven per cent over 1959. They totalled 6,970, says the annual report on accidents issued by the Transport Ministry and Scottish Home Department Serious injuries rose by five per cent to 84,443.

Other points in the report: There were 22 killed and 161 badly hurt on the M1 during its first year of operation.

## New British Guide Book For Travellers Features Nigeria

LONDON–Detailed information about Nigeria and Ghana that will be invaluable to the traveller is included in the new edition of Travellers Digest – the B.O.A.C. guide book. Five pages are devoted to Nigeria's "light hearted, affectionate people in colourful dress" its history, people, climate and clothing, hotels, food and drink, sport and entertainment, facilities and shops.

The digest is directed particularly at people travelling for pleasure and is concisely and informatively written, with a light touch which make it entertaining reading as well.

## British Professor To Teach At Ife University

SCOTLAND – When Dr. Robert H. Cairnie, head of the Department of English at Queen's College, Dundee (St. Andrews University) takes up his new appointment to the chair of English at the University of Ife, on 1st September, it will fulfil an ambition he has long cherished.

"I have been feeling for some time that I would like to work in Africa and I am particularly looking forward to taking a position in a new university in a new county," he told our correspondent recently.

"The job presents many interesting and exciting possiblities, while the prospect of living in Ife–the ancient spiritual capital of the Yoruba people – is very stimulating. I am hoping to have time to delve into its archaeology, and I want to see some of the famous the bronzes and terracottas," Dr. Cairnie added.

During his five years at Dundee and in the two previous years at Bedford College, London University, Dr. Cairnie has met many Nigerian students for whom he has a high regard.

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT:
IKORODU TRADINN COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

## Eru Aiye Ma Mba Mi!

(O bere loju ewe keji)

Ogbeni na se iwon ti ole se, a si wa ri wipe aiye na yato die fun igba de ti Ogbeni na gbe laiye asehinwa-asehinbo aiye na ni opa Ogbeni na. Mo beru aiye o, aiye ti ko je ba ni la owo eje, afi owo epo, aiye ti ko feni fe oro, af'ori eni, aiye ti o ma ngbe enia gun esin ayan, aiye ti inu re ma dun si isubu enia, aiye ti o gbe enia gun ori igi tan, ti o tun ngee ni isale, aiye gba jeje aiye soro! aiye lo nso igba di ogbun, igba kan ko ngbun l'oko. Mo beru aiye o.

Ko iti pori

---



## Plushes, Velvet, Velveteens, Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

## Okunowo Brothers

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.



---



Advertisement No. 76.

## KERE O

OFIN TI A NFI NA OWO

ATIJO (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS)

DI PI PARE

A fe la ti ran gbogbo enyin enia leti wipe lati ojo Kini osu July, 1962 (Osu keje odun yi) gbogbo Owo atijo patapata eyi ni owo Pepa ati owo Sile titi de ori Epini yio kuno. Ako ni le lo won gege bi ofin ni ile Nigeria.

Eyi ni wipe lati ojo Kini osu keje (July) odun yi, Owo atijo wonyi koni wulo fun sisan owo fun ise aje ni jake-jado ile Nigeria – fun apejuwe, akoni gba fun oja rira tabi fun oja tita ninu oja ati sopu.

Gbogbo eni ti o ba ni owe atijo wonyi lowo tabi o ipamo yala ni Pepa tabi ni Sile ni lati tara lo se pasi paro owo wonyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti Central Bank ti Nigeria fi sita ni nkan bi odun keta sehin, ti asi nna lowowoyi ki ojo Kini osu keje odun yi (July) to to - Ofe ni gbogbo Bank yio paro Owo wonyi fun yin.

JOHN BEACH
Deputy General Manager.

Central Bank of Nigeria,
Lagos.



Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23378; Olola L. A. OJO. 12 Inabere Street, Lagos.

## Ikede Ofin Pajawiri Ni Ipinle Iwo-Orun Nigeria

EKO-Ijoba Apapose kede ofin Pajawiri lati enu Olotu Ijoba Olola Sir Abubakar Tafawa Balewa ninu Ile Igbimo nla nilu Eko ni ojo Atalata (Tuesday) ojo kokan-din-logbon osu May, 1962.



Dokita Majekodunmi

Ile Igbimo gba ofin na lehin ti Olotu Ijoba se alaye wipe nkan ti o ti nsele lati bi ose meji s'ehin ni Ipinle Iwo-Orun ti o fa rogbodiyan ija ote wa ninu Ile Igbimo Asofin Iwo-Orun ni ojo Jimoh (Friday) fihan gbangba wipe ko si eto Ijoba atata ni Ipinle na. Ise ti Ijoba Apapo ni ki a ri pe Ijoba alafia pada si ipinle Iwo-Orun, a ko ni nkankan pelu oro edeaiyede won.

Olola Sir Abubakar ke si gbogbo awon Olugbimo wipe ki nwon fun Ijoba l'agbara lati le p'etu si rogbodiyan ipinle Iwo-Orun na ki o mase le gb'eru siwaju.

Alase Ise Ilera, Dokita. M.A. Majekodunmi ni Olotu Ijoba yan lati g'ori aga akoso ijoba ipinle Iwo-orun Nigeria, awon Ile Igbimo nla ati ti awon Agbe Oselu si f'owosi. Ni ojo Alamisi ni a gbo wipe Dokita Majekodunmi lo bere ise re nilu Ibadan.

### IWE ASE IHAMO

Awon enia bi ogoji ni a gbo wipe yio gbawe ase ihamo fun asiko ti nwon yio fi se eto Ijola alafia si ipinle na, awon ti nwon ti fun ni iwe ni Oloye Obafemi Awolowo, Oloye S.L. Akintola pelu awon alatilehin won.

### IBADAN GBALEJO

Nigbati oko ofurufu ti Alakoso Ijoba Iwo-Orun, Dokita M.A. Majekodunmi wo gunle silu Ibadan, ni deedee agogo marun ku iseju medogun, ti Oba Akinyele, Olubadan, ati awon Oloye re pelu awon enia jankan-jankan lo pade re ati awon Olola Ogbeni T. O. S. Benson pelu Ogbeni Akinfosile.

O ba ara ile Iwo-Orun soro lori ero asoro-magbesi wipe, on wa lati wa wo egbo ti awon ti iselu npa bi oti da si ipinle Iwo-Orun ni, ki ise bi asegun tabi a da ase pa, paapa omo wale ni on je ni ipinle Iwo-Orun. O kesi Imale ati Onigbagbo fun adura ni ojo Jimo ati ojo ose, ki Ijoba alafia ati ase rere le pada si ipinle na.

---

## Oku Olomo Gege L'a O Gbe

Orile Oshodi-- Ni ojo Tuesday ojo kejile logun osu May, 1962, ni a gbo iku Ogbeni Alimi Akano Emiabata Ajenifuja ti a mo adape oruko re ni Baba Ebute ni Ebute-Metta, nwon si sinku re pelu eto esin Musulumi ni ojo Wednesday ti ise ojo ketalelogun osu May, ni Opopo Araromi, Agbala Bale, Orile Oshodi.

Ese awon ebi, ore ati ojulumo ni o pe siba-siba sibi isinku na, Immam Abudu Karimu ti Orile Oshodi ni o se etin isinku re, awon Immam ati janmo won ni o wa lati awon ilu bi Eko, Ebute-Metta Mushin, Mofoluku, Agege ati awon opolopo ilu ti o yi Orile Oshodi ka, ese kogbeji ni a le pe ojo na.

Lehin ojo isinku, gegebi asa ti awon ara Eko nse. "Ojo ose ijoko" eyiti nwon npe ni Sitting Sunday, ni ede Oyinbo ti nwon se ni ojo ketadin-logbon osu May, buayfi, o le gongo. Inawo ojo na pa bambari!

Die ti a le daruko ninu awon omo oloku ni Saturatu Aasbi, Kaliatu Amope, Muhammed - Raji Akanni, Yekini A. Ajenifuja, Suwebatu Amope Nusiratu Aduke, Tawaliu A. Ajenifuja, Nimotalahi Abdul Fatayi ati Ogbeni wa Lamoriyu. A. Ojo, Olori ebi ti ise Olotu Iwe Irohin wa, Eleti-Ofe yi, ni nwon nawo, ti nwon si fi ohun jije ati mimu te ogunlogo awon enia lorun.

Ki Olorun gbe ologbe na si afefe rere – Amin.